# EKO AKETE.

## IWE IROHIN OSOSE.

ỌRỌ IFOJUSUN:—
"Emi yio fi ohun ti o dun Makunnu han awon Alagbara, Ngo si je Alagbawi awon Odi".—W. T. Stead.

Vol. I. No. 34. SATURDAY, MARCH 3, 1923. Fourpence.

*Editor & Proprietor:—*
ADEOYE DENIGA,
*Office:* 24, Williams Street,
P.O. Box 286,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.

N. V. HANDELMATTSCHAPPIJ V. H.

J. F. SICK ati AWỌN ẸGBẸ.

No. 7, Ita Ibode lailai, l' eti *Glover Memorial Hall* (*Customs Street*,) EKO.





Awọn Oyinbo Onişowo yi nranşẹ Masini-aranso ti a npe ni VESTA Nos. 1-4 t' ọlọwọ ati t' ẹlẹsẹ ni owo to rọju a le fi iye-owo wọn han ẹnikẹni to ba lọ si Ile-owo yi.

Nwọn mura tan lati şe adehun pataki pẹlu ẹnikẹni to ba fẹ ranşẹ Mejila tabi jubẹ lọ ninu Masini na.

Awọn Oyinbo yi nşe orişirisi Ilẹkẹ alarabara, nwọn si nranşẹ *Cement* ati panu kikọle tọ nipọn, ati ẹja Abọmafọ ati orişirişi ọja

Ilẹkun Ile awọn Oyinbo yi şi nigbakugba ti enia ba fẹ lati lọ ba wọn sọrọ Asiri nipa Owo. Irohin ko to afojuba.

## Ile Ita Egbogi ti Macaulay.

*(Macaulay's Household Dispensary.)*

A nta orişirişi ogun Ilera ni Ile-oja yi, to wa ni opopo-nla (*Broad Street,*) l' Eko ni owo po ọ.

Awọn Ogun bi Oko, Painkiller, Ogun Inarun Ogun Lakoregbe, Ogun Koruna, Ogun Aran to dara Ogun Ẹda, Ogun Arẹmọ.

Ọgbẹni S. A. Q. Macaulay ẹniti oni Ile-Egbog yi je ẹniti o gba *Aşẹ ogun pipo* (*Certificated Dispenser.*) lowo Ijoba Nigeria.

Ẹ LỌ DAN A WO, Ogun rẹ jẹ bi idan.

---

## ỌGBẸNI J. C. VAUGHAN.

Ti Ile-Ọja Sheffield ni Ita Kalawa ati Ile-Ọja "*Excelsior*" ni Ita Agarawu, ni oniruru awọn ohun kikole fun tita ni owo ẹpọku-ọyọku.

O ti nşowo Irin Işẹ lorişirişi lati adọta ọdun sẹhin titi di oni.

ATARI AJANAKU ni ỌGBẸNI na jẹ ninu awọn onişowo Irin Işẹ ni ilu Nigeria.

ỌKỌ tita wa ni owo po ọ.

---

## ỌGBẸNI DURO: THOMAS.

ONIŞOWO PATAKI.

Ti 55, Ita Faji, l'Eko, ni orişirişi Ọja to de fun u lati Ilu Germany fun tita: awọn nkan Awo abọmafọ, Cement, Akara, ati ọpọlọpọ ọja miran.

Ẹ lọ de ibẹ, Igbo-Akan 'mọpa ni ohun to ni.

Bi ẹ ba fẹ, ẹ kọwe si i, *Number* Apoti-Iwe rẹ ni Ile ipin iwe (*General Post Office*) ni *374*. *Number* fifi-ẹrọ manamana ba a sọrọ (*Telephone*) ni 243.

---

## Ẹ WA RA ỌPỌ ỌJA

Ọgbẹni D. B. OŞUNTOLU, onişowo Ọlanrewaju ni ọpọlọpọ ọja fun tita ni Şabu rẹ ni No. 44 Balogun Street, l'Eko.

Ninu awọn ọja rẹ ni iwọnyi:—Ikoko taba, Carpets Panu ikọle, Aşọ oniruru, Itẹko, Baranjẹ, Olowonyọ, Yọmini. (*Satten*,)

Ati orişirişi nkan atata miran, Ọja Ọgbẹni yi rọju o si lere ninu, ọpọku-ọyọku ni.

Ẹ lọ ra ti nyin nibẹ.

---

## WHAT IS MORE REFRESHING than a sound sleep on a comfortable Bed? or time-saving than a thoroughly good sewing-machine?

A large consignment of Brass Iron-Beds, Bedsteads, (new arrivals from Germany.) hand and Treadle-sewing machines "Gritzner" is just to hand at Mr. Duro. Thomas's establishment 55, Massey St., Lagos.

An early call at this address for your selections will well reward your labour.

Prices attractive and alluring.

CALL TO-DAY NOT TOMORROW.

---

## KILO NGBE MI LỌ YI O? ORUN!

AŞỌ NYIN FAYA, Ẹ LỌRAN.

AŞỌ NYIN FAYA, Ẹ LỌRAN.

IBUSUN-ILESANMI ati MASINI-A-NJUWON

Ọgbẹni DURO THOMAS.

Onişowo-towolawi, ni awọn IBUSUN mèrémèrè onidẹ to şẹşẹ de fun u pẹlu awọn MAŞINI iransọ ti a npe ni *Gritzner* ti ọlọwọ ati ti ẹ'ẹsẹ, lati ilu Jamani wa fun tita ni Ile Ọja rẹ 55, ita Māse leti ita Faji, l'Eko.

Ifà mbẹ fun awọn to ba tete lọ ra tiwọn nibẹ: owo yẹpẹrẹ ni a nta wọn, bẹni awọn Ọja na si "ka 'yin" to.

Ẹ lọ ba Àwúre nyin pade nibẹ.

## GBOHUN-GBOHUN.

:o:

B' A LE NI BA A BA NI,
IWỌN LA NBA NI Ṣ' ỌTA MỌ!

Gẹgẹbi a ti mọ ikorira ti Ọgbẹni Ọlọla Kitoyi Ajasa ni si Eṣugbayi Eleko lati igbati ijangban ti de ba Ọmọ-Alade na lẹnu ọdun diẹ sẹhin, ẹnu ko ni ya ẹnyin ara ilu lati gbọ pe ninu Ipade-ijọba ti *Nigeria* ti a ṣe ni ọjọ *Monday* ọsẹ yi eyiti, Ọgbẹni na jẹ ọkan ninu *member* Ipade na, Ọgbẹni ti a wi yi ninu ọrọ rẹ da Ijọba nimọran pe ki nwọn mu Eṣugbayi kuro ni Iga Idunganran gẹgẹbi nwọn ti ṣe si Oloye Aliu ni ilu Hausa ati si Oloye Aṣọgbọn ni ilu awọn Mahin. Ọgbẹni yi tun sọ pe, bi Ijọba ko ba gba bi on ti wi yi, o ni tẹmbẹlẹkun ko ni tan ni ilu ṣugbọn a dupẹ pe gbogbo awọn Ọlọla ẹgbẹ rẹ ti o tun sọrọ lẹhin tirẹ, titi kan Gomina Agba Sir Hugh Clifford, ko si ẹni ti o ba Ọgbẹni na pẹkẹlu imọran rẹ yi.

Ni tiwa, irufẹ iwa yi ku diẹ koto. Bi rudurudu ba wa ni ilu gẹgẹbi Ọgbẹni yi ti wi, kini awọn Olori Ọlọpa-Ọba wa fun o? a bere bi alaimọ. Ẹnyin ara ilu, ẹ ko wa ri pe ẹhinkunle l' ọta wa, Ile ni aṣe ni ngbe? eyi bayi mu wa ranti Odu-Ifa kan ti awọn Baba-lawo ma nki bayi pe,..." Ara ile ẹni ni iro ni fun ero ọja, ero ọja ni iro ni fun agunfọn, agunfọn ni imu wọ 'gbe lọ sọ, a ni, ọrọ rẹ! ọrọ rẹ!! ọrọ rẹ. !!!"

Ẹ KABỌ OJỌ!!!

A ba awọn enia wa to wa si Ipade igbimọ ti Ijọba *Nigeria* eyiti a po-longo rẹ lẹnu ọsẹ meji to kọja, yọ fun lilọ ti nwọn lọ sibẹ. Kosibotiri ni ajọ na, awa papa ṣakiyesi bi awọn enia wa ti mọ 'di si ẹnu ọna Gbangan na, ti nwọn si gbọ orisirisi ọrọ nipa iṣe 'lu ti Gomina agba Sir Hugh Clifford sọ, titi o fi kan awọn *member* miran. A ri nigbati Gomina bojuwo awọn enia wa wọnyi ti ko si sọ pe diduro wọn tabi wiwa wọn nni on lara. Ti a ba nlọ si irufẹ Ipade bayi ede-ko-yede ati ọrọ-isọkusọ yio dinku ni ilu. Gbogbo rẹ ko tilẹ to igbati Gomina agbaanbọ bi "arira" ninu Kẹkẹ-jẹlẹ-nkẹ, ti awọn ọmọ-ogun pẹlu awọn Ọga wọn dà fere fifun si 'lẹ: o mu ki ori wa wu! Ipade na bẹrẹ ni agogo mọkanla fi iṣẹju diẹ kọja larọ, o si pari ni iwọn agogo kan ọsan Ile kun bibà.

ONILU KO FẸ 'O TU.!

Ohun ti a gbọ pe a pe awọn Ọmọ-ọba ati awọn Ijoye Onifilafunfun si, ni Gbangban Igbimọ-ijọba ni *Saturday* ọsẹ to kọja ni lati sọ nipa ti Olori Iga-idunganran: Ọgagun H. C. Moorhouse, C.M.G. igba kẹta Gomina ni o ṣe alakoso ipade na: awọn ti a sọ pe nwọn sọrọ ni Iya-afin Kuyẹ ọmọ Ajọsẹ, Oluwa Oloye, Sunmọnu Faro, *Lawyer* Mobọlaji Akin-ṣemọyin, Ibikunle Akitoye Ọmọ-ọba, Ọgbẹni John Kosọkọ ti Iga Kosọkọ. Oloye Ọbanikoro ati awọn Oloye miran wa nibẹ pẹlu. A wipe awọn miran nfẹ ki a mu Eleko kuro ni Iga-Idunganran ati pe ẹniti tirẹ yọyẹ ninu wọn ni Iya-afin Kuyẹ awọn miran si kọ ọrọ yi patapata agbare-gbabọ Ipade na ni pe pupọ ninu awọn to lọ gba Ọgagun Moorehouse lẹsẹ mu ki o ba le ba wọn bẹ Gomina-agba lati foriji Eleko ko si pe e sipo rẹ pada.

AWỌN ẸGBẸ MIMỌ NKỌRIN
OGO, OGO, OGO.

Anu ṣe ni lati jihin iku Ọgbẹni Adekọya ọkan ninu awọn Olukọni ni Ile-iwe Faji, to ṣelẹ ni ọjọ *Monday* ọsẹ yi, a si sin i ni ọjọ kanna ni Ikoyi. A ba awọn Alaṣẹ ati awọn Olukọni na kẹdun iku ọdọ yi.

K' A GA A, K' A GO O, EDE NI KO Y'EDE.

O ya ni lẹnu gidigidi lati ri pe ọrọ-ipolowo-nkan bi "Ara ilu gba k' ẹ tọ wo, oyin mọmọ" ti o han ninu Iwe-irohin yi ni igba kan, le jẹ ohun ti ọrẹ wa

Ọgbẹni C. B. Olumuyiwa le sọ ọrọ odi si nigbati o nsọrọ ijiyan rẹ nipa awọn Iwe-irohin Eko, ni *Grammar School* ni alẹ ọjọ *Thursday* to kọja. Njẹ ti a ba ba ọrẹ wa yi yọ pe "Aiye ẹ lo ndun bayi?" (nipa ti gbigbega ti a gbẽ ga ninu ipo nibi iṣẹ rẹ ni lọlọyi) isọkusọ ma'ni yẹn? A ko gbọdọ sọ pe ọrẹ wa na jẹ alaigbede nitori ọmọ Yoruba-fau-fau ni gẹgẹbi apele orukọ rẹ ti fihan.

Nitorina a ro pe nkan ti ọrẹ yi sọ nipa tiwa ni alẹ ọjọ na, o fi ṣ'ètè lọṣọ ni.!!!

### AṢEJU BABA AṢETẸ.

A ji sọ fun ni pe awọn diẹ tun nmura nisisiyi lati lọ si Ilu-ọba fun iṣẹ Lọya: njẹ iṣẹ Lọya ko ṣẹ ndi yẹpẹrẹ baun? lotọ, irufẹ awọn ẹni bayi le wipe ṣe nwọn ko gba owo lọwọ wa lati mu lọ: ṣugbọn ko si ẹniti ko mọ pe ohun kanna ni tita l'ọja okuta lo nmu wa: bi a ti ba nkan yi lọ yi, njẹ Lọya ko ni ma ṣe akọwe Lọya nigbati o ba ṣe bayi? a ko gbadura pe ki Lọya mã ka igi Ajà. Ohun ti a nfẹ tẹ mọ awọn ara wa leti ni pe ogunlọgọ iṣẹ miran lo wa ni kikọ ju kiki iṣẹ A-ntutọ-soke, a-nfojugba lọ.

### KABỌ, ỌMỌ ATOBAJẸUN.

Ọgbẹni Ayọdele Williams ọmọ Ọgbẹni Obi Williams Ologbe, pada bọ wa 'le ninu ọkọ "Aba" to de sibi lati Ilu-oyinbo lojọ *Friday* ọsẹ to lọ, lẹhin igbati o ti "yege" iṣẹ Lọya tan. Ọmọ Akọwe-kọwura, Baba rẹ a gbẽ ọ o.

---

## IRIN-AJO LATI EKO LỌ SI KAMERUN. II.

Bi ilẹ ti nṣ'okunkun biribiri bẹni ọkọ wa sunmọ ara Kereni, ẹniti ki iba ṣe ara ilu Calabar, ko da mi loju bi o le rin ilu na l'oru, nigbati awọn ti o jẹ ara ibẹ si nsọ pe o di arọ ọjọ keji ki awọn to k' ẹru sọkalẹ, mo pinnu pe ngo fi bibọ silẹ mi ati rin kakiri d' ijọ keji.

Bi ilẹ ijọ keji ti nmọ, ti a ti ṣe ọlọjọ inu tan, ebi ko ṣa npa ni ki ọro miran wọ, mo wa bẹ si ori Kereni o di arin ilu. Ilu Calabar jẹ ilu ti o wa lori Okiti, ẹniti o ba si nṣ' akiyesi, yio ma ri pe omi ọsa ti o wa wa l' ẹgbẹ iru ilu bayi le jin pupọ, omi Calabar jin, ko si ṣe yaju si, nitori eyi, ọkọ lọ si ilẹ dada, nigbati mo jaja wa awa yida ti mo wọ arin ilu yi, o mu mi ranti orin ọmọ kiriyo kan ti ima kọ pẹlu *Guitar*, ọrọ orin na lọ bayi pe:—

Nigbati mo ngbọ Calabar
Mo ṣe bi 'lu oyinbo
Nigbati mo de 'bẹ
Ẹru Ọlọrun ba mi
Bo de bi, koto rẹ
Bo dọ hun, gegele
Ilẹ ọmọ Effik
Ilẹ ọmọ Calabar.

Oke, gegele, afonifoji, bẹni ilu yi lọ titi niyẹn, ẹniti ko ba ni igboiya dada ko ni pẹ ma rin ani duro lati sinmi, nigbati mo jaja wọ titi mo wa de ibi inu *Church* kan nibẹ *Trinity Church* ni orukọ rẹ, *Church* yi jẹ ti *Missionary*, mo wọ inu rẹ lọ, mo si gbadura si ọdọ Ọlọrun fun ṣiṣọ rẹ l' ọsan l' oru larin agbalagbulu omi okun.

Nigbati mo ti kepe Ẹlẹda mi tan, mo wa f' oju silẹ lati woran nitori a ti ngburo *Church* yi l' Eko ti pẹ, diẹ ninu awọn Alufa ti a mọ dada sa ti ṣiṣẹ nibẹ ri, awọn bi Alufa Doherty ti o wa ni Kudẹti Ibadan nisisiyi ati Alufa Johnson ti mbẹ ni Arọloya.

*Church* yi, laiṣe ani ani yio gba to irinwo eniyan, nwọn ti fi panu kọ lati ilu oyinbo, nwọn wa ti nihin ṣa ni, awọn ijoko inu rẹ jẹ *chair* at'apako, nwọn si to o minimini dada, ọna meji lo wa ninu rẹ; ibi iduro si Alufa kere diẹ, o fẹrẹ ma to ti St. Peter dada, *Organ* oni ipe kan wa nibẹ duru si wa nibẹ pẹlu, o dara pupọ, mo gbọ pe oruko Alufa wọn nisisiyi njẹ Renner. *Church* na ko jin pupọ si adugbo ti nwọn kọ ile awọn akọwe si.

Mo wa ri ẹnikan, mo sọ fun u pe mo fẹran *Church* pupọ, emi papa si nlọ ni ilu mi ti mo ti jade, ibẹ la ti bẹrẹ ọrọ, o ni *Church* yi ti akun dada ri, o ni ṣugbọn iyọnu kekere kan wa nisisiyi, mo ni sọ fun mi ki nbula, iru iyọnu wo niyẹn, o ni ikanu ti o ma nmu iyọnu wa si *Church* ni, o ni laipẹ yi Bishop Howells wa si ibẹ, o si lo ofin *Church* fun ọpọlọpọ awọn aṣaju nwọn ti o jẹ pe awọn ni ẹni *Church* na. O sọ ọrọ wọnyi tẹdun-tẹdun. Mo wa sọ fun pe iṣẹ Bishop ni Bishop ṣe, awa enia dudu ti a mọ iwe diẹdiẹ ni lati bẹrẹ si mọ pe, igba aimọ ti kọja ti a le ma fi oju fo ẹṣẹ iru iwọnyi ti *Church* kọju ija si, ẹniti o ba si ti mọ pe ofin ti *Member* ni lati tẹle yi le ju eyiti on le ṣe lọ, ki o kuro ninu *Church* tabi ki o mu ipo ẹhin, ọrọ mi yi ko dun mọ ọkanrin yi leti o ṣa nsọ ku u, mo wa sọ fun u pe,

u tirẹ lo wa yi, bi mo ba nba ọ jiyan ọrọ ti ko kan ni titi, akoko oujẹ yio kọja, ngo si ni iya ni ilẹ Effik ti yio bọ mi, bẹni ngo si le fi iyan ọga jẹ lasa, o ti, ngo le ṣe.

Ibẹ la ba pin gāri, ni mo ba gbọ'na, ka nfọ ilu kiri, mo rin titi o rẹ mi, mo kuro ni agọ ti awọn enia dudu, o di adugbo ti awọn oyinbo. Owo ti nwọn na sibẹ ko kere, ilu nlanla pẹlu ọgba jankan-jankan—gbogbo rẹ tẹ lọ bẹrẹbẹ—koriko daradara si hu lọ salalu bi ti ọdan, aiye nbẹ nbẹ o jare, mo fẹrẹ le sọ pe ki lo mu mi lọ gba ibiti awọn ara ilu yi goke, ti nba ti gun ti oyinbo ṣa ki nṣere diẹ ki nto sọkalẹ. Mo rin titi mo de ibi ile itawe wọn, iru ti Eko, a mọ awọn onişẹ Ọlọrun miran ti o yatọ si ti Eko loni, nwọn njẹ *Hope Waddell Institute* bo ba ri awọn Calabar Akowe ninu *Shop* wọn, nişe ni nwọn nlọ aşọ mọ idi ti nwọn wọ *Shirt* awọleke le 'ri rẹ, ninu awọn Olukọ ninu ile-iwe yi, bẹ na ni nwọn wọ aşọ, ati ninu awọn ọmọ ile-iwe papa. Mo ni eyi ma ş'ara kẹ.

Nigbati mo sọkalẹ wa mo gba ọna Marina mo rin-rin titi mo de ibi *Shop* awọn oyinbo, o pọ lọ sua l' oniruru bẹ si ni awọn enia dudu pagọ bẹrẹbẹ lọ niwaju nwọn bi ti Ẹhingbẹti l' Eko, işu nla-nla, ati oniruru nkan ni jijẹ mimu ati wiwọ lo kun ile ọja wọnyi, igbati ilẹ şu şa ti nko riran mọ ni mo wa pada sinu ọkọ ka wa lọ sinmi.

Gẹgẹ bi orin ọmọ kiriyo, bi enia ba ngbọ "Calabar" "Calabar" lati ijọ ti a ti ngbọ yi, ko ni l' ero pe ko ni lari tobẹ; papa nibi agọ ti awọn enia dudu, gbogbo rẹ ri pagunpagun, ọpọlọpọ ile ti o wa nibẹ papa ko şẹ ni, ki a ma tan ara ẹni jẹ ilu ti ao fi we Eko, tabi ilẹ Yoruba, o di şaşa, ki işe ni gbẹgbẹlẹ wa yi.

AJEJI.

*Koi li'pari*

---

## KI ẸNITI A BA WI FUN KO FẸ O.

Bi mo ti yọju loju ferese mi lowurọ ijọ kan, mo ri awọn ọmọkunrin meji ti nwọn nbu ara wọn, lẹhin na nwọn tun nbu baba ati iya ara wọn, mo si kilọ fun wọn pe ayanga nyin, nko gbọdọ tun gbọ ki ẹ bu ara nyin tabi awọn Obi nyin mọ, mo ni ẹ yara tuka nibẹ. Nwọn pẹsẹda bi ebe meji, lẹhin na, nwọn tun bẹrẹ ebu wọn. Bi iti iri larin awọn onija meji, ẹnu ẹnikan mu ju ti ekeji lọ. Mo nwo wọn şa. Nigboşe nwọn kuro lori ebu, o di pe nwọn nfẹ lu ara wọn. Ọkan ninu awọn mejeji wọnyi mura kikan, o nleri ija, o nfọ gbo, ẹnikeji rẹ mura giri, şugbọn ko fẹ ja nitori bi mo ti kilọ fun wọn. Nigbati aşẹju eyi ekini npọ, ekeji wa sọ fun pe, "Iagbaja, o tẹ" nwọn sunmọ ara wọn lati ja, nko fọhun, mo kan nwo wọn. Nigbati eyi to ti dakẹ sunmọ ekini to le gbonu, o fi tagbaratagbara gba a leti lai! Eyiti o ngbonu yẹn wa fọwọ mu eti, o ni "La illah!" Ko ta putu mọ, emi ati awọn to wa nitosi bu si ẹrin oju wa ti i, mo ni, o ko wi i tan, o ku ki o wipe Illah lahu!! A şe "La illah" a ma bọ lẹnu rẹ ni mo kilọ ija fun nyin ti o ko gbọ? Ẹniti a ba wi fun ki o fẹ, bi ko ba fẹ, yio ri ẹtẹ ati itiju. Ọmọ yi si fi itiju pupọ rọju pẹsẹda, o gbọna ile rẹ. Ẹniti o ba ri ẹni sọrọ fun on, ki o jare tete gba ni gba ẹyẹ o.

---

## OUR NEW ARRIVAL.

We welcome into this country once more, Herr Otto Brukwoldt a partner of the Firm of Messrs C. Woerman Ha mburg.

Prior to the late War, Herr Brukwoldt was holding in Lagos, the very responsible post of Agent or Head of the old German Shipping Company—Woermann—Linie: his present visit is in connexion with his new Firm's business whose local representative is our respected towns-man Duro Thomas Esqr. of 55, Massey Street, who has left no stone unturned in providing our visitor with every comfort during his short stay with us.

It was our privilege, lately, to have the gentle-man introduced to us, and we were particularly struck by his unassuming, yet *genteel* manners and affability.

As a business man, Herr Brukwoldt is shrewd but yet keen, with winning smiles which cannot but drive away the "blues" from any would—be client coming in contact with him commercially.

We have no doubt that on our friend's return to The Vaterland, he will carry away with him many happy recollections of his short but crowd-ed time on our shores :—

---

## POPO MỌKA MỌ RORO, ALIJANNA N'ILE WA!

A ba awọn ẹbi Ọgbẹni Braimah Adagun kẹdun iku ọgbẹni na to şẹlẹ ni adugbo rẹ Ita Adagun ni Alamisi ọsẹ yi. Ẹsẹ ko gbeji nibi oku na.

**EKO AKETE.**

EKO, SATURDAY, MARCH 3, 1923.

## B'O ṢOJU WÈRÉ, Ẹ F'Ọ̀GÀ GBE E.

Irufẹ orin ti awọn enia wa ma nkọ fun gbigbe oku lọ si Itẹ ni a kọ nigbati a lọ si Ipade Igbimọ Ijọba ti Nigeria ni ọjọ *Monday* ọsẹ yi ti a ṣe ni aṣe-kẹhin. Igba yi lo jẹ igba kẹjọ ti Ijọba ti nṣe ipade na. Nigbati a si de gbangan ibiti a gbe ṣe e, ṣeranwo ni! gbogbo awọn *Member* to pe'sẹ sibẹ jẹ 16: Gomina Agba Sir Hugh Clifford G.C.M.G., lo si jẹ ẹni kẹtadinlogun wọn. Gomina Agba sọrọ lọpọlọpọ nipa ti ohun pupọ to ti rekọja lati igbati nwọn ti ṣe irufẹ Ipade bẹ lọdun keji ọhun: o fi ẹnu kan ọrọ Eleko pẹlu ẹdun-ọkan, o si sọ pe anu ṣe on lati wipe ko si atunṣe mọ nipa rẹ: o si sọ ti Igbimọ Titun ti Ijọba npete ati dasilẹ lọdunni.

Lẹhin eyi ni Ọgbẹni Ọlọla Kitoyi Ajasa, dide o si kan sàra si Gomina Agba fun Iwe-ọdọdun rẹ (*Address*) to ṣe eyiti olukuluku awọn *Member* Ajọ na ti ni ni ọkọkan. o tẹnu mọ ọrọ Eleko gidigidi pe pe ki Ijọba mu u kuro ni Iga Idunganran: o si sọ pe ki Ijọba sofin kan ti yio di apakan Iwe-irohin ni ilu lọwọ ki nwọn ma le sọ ti inu wọn ni ọna ti irufẹ Iwe-irohin bẹ ba ro pe o tọ lati sọ si awọn ti Ọgbẹni na ni nwọn jẹ onipo tabi alaṣẹ Ijọba: o sọ ọ mọ ọrọ pe awa Yoruba jẹ ẹniti o "sábà" ati ma bu ọwọ ati ọla fun awọn ẹni-ọla tabi onipo larin wa, ibaṣe dudu tabi funfun: o gbe ẹnu le Iwe-irohin kan to jade ni lọlọyi o si sọ pe ọrọ ti a sọ si Alaṣẹ Ijọba Ilu lara nibẹ ko jẹ ohun ti o wọ fun on rara: A fẹ bere gbolohun ọrọ kan tabi meji lọwọ Ọgbẹni yi. (1) Nigbati ọgbẹni yi sọ sinu Iwe-irohin rẹ *Nigerian Pioneer* ti ọdun diẹ sẹhin pe ọmuti ati onijẹkujẹ ni Eleko, njẹ ọgbẹni yi to jẹ ọmọ Yoruba ma nbọwọ fun Eleko ni yẹn gẹgẹbi onipo tabi ẹni-ọla? (2) Ẹwẹ, nigbati ọgbẹni yi si sọ ninu Ajọ Igbimọ ti Nigeria yi, ti a ṣe ni ọdun 1920, ti a si tẹ sinu Iwe-irohin Ijọba ti ọdun na, pe Eleko dabi oku-igi, ati pe yio jẹ iṣẹ Ijọba lati ge oku-igi na lulẹ, njẹ Ọgbẹni yi ma nbọwọ ati ọla gẹgẹbi iwa awa Yoruba fun Eleko niyẹn, gẹgẹbi onipo tabi ẹni-ọla? Ẹnyin ara wa, ẹ gba ọrọ yi ro.

Gomina Agba ninu Iwe rẹ (*Address*) ninu ewe 35 nibiti o gbe sọrọ Eleko, ko daba nkan ti Ọgbẹni yi daba rara: ẹ ko wa ri pe ẹjọ awọn Oyinbo olõre ati ọrẹ wa kọ. Awa ara wa la nṣe ara wa !!!

Ọgbẹni Ọlọla Rhodes (Oyinbo) ṣe bẹbẹ ninu Ipade yi: o tako apakan Iwe-ọrọ Gomina na ni ọna to tọ "súnà" o si fi ohun ti o ro pe o jẹ afoju-foda han gbogbo Ajọ na: Ọgbẹni yi si sọ nipa ti Wiwo-ekurọ ni ilu Ọke ati ṣiṣe ọna fun ọ̀wọ̀, Ọgbẹni Ọlọla Richard Henshaw (ara Calabar enia dudu) dide sọrọ: o dupẹ lọwọ Gomina fun Iwe-ọrọ rẹ, o ni gẹgẹ bi a ti fẹ sinku ogbologbo Ajọ yi nijọna, on tanma pe Igbimọ titun to nbọ yio tubọ ṣe *Nigeria* ni rere siwaju ati siwaju. Ọgbẹni Ọlọla Archer (Oyinbo) sọrọ nipa ti owo Ọkọ-omi ati ti ilẹ ati owo ẽdu. Ogbẹni Ọlọla Brown (Oyinbo) sọ ti pasẹ didinku tabi piparẹ owo ti awọn Oniṣowo nsan fun Ijọba (*Export Duties*) ti ọgbẹni na ro pe o jẹ inira: Ọgbẹni Ọlọla Ajasa gbe e lẹsẹ: ṣugbọn Ọgbẹni Ọlọla John Scott Adele Ṣẹkitẹri Agba ti Ijọba fesi si ọrọ yi ni ọna to wọ̀, Gomina-agba si gbe e lẹsẹ o si tun sọ pe ohun ti Ọgbẹni Ọlọla Brown mu wa fun yiyẹ wo ko le ṣẽṣẹbi nkan ti wa nisisiyi, ṣugbọn o le jẹ ṣiṣe nijọ miran.

Lẹhin eyi, Gomina-agba ṣọpẹ lọwọ awọn Ajọ na fun ọrọ iṣiri ti nwọn sọ si Iwe-ọrọ on, o si tun sọ pe ko si ẹniti piparẹ Igbimọ yi le dun, nitoripe on ko ro pe o ti nṣe rere kan lati igbati Gomina Lugard ti o ṣaju on nibi, ti da a silẹ: o si wipe ti enia ba ri pe nkan kan ko wulo fun on, o yẹ ki oluwarẹ yago fun nkan na: Gomina si tun wipe, lati ọjọ *Monday* ọsẹ yi lọ Ajọ Igbimọ ti *Nigeria* di oku.

*( Ẹ wo oju Iwe 8 )*

# SINGER ! SINGER !! SINGER !!!



Kinla! Tiwa ki nṣe a nṣẹṣẹ wa onibara, kini a ti nṣ'oku l'ọrun, nwọn pọ to wọbu larin oriṣiriṣi enia jakejado Nigeria.

Ẹrọ iranṣọ "SINGER" kọkan, ni gasikia polowo ara rẹ.

Pataki ohun ti o mu 'Ẹlẹha jade ọsan' ni wipe a nfẹ mu wa si akiyesi awọn ogunlọgọ onibara wa

TI ẸDINWO NLANLA TI A ṢE

ninu owo ẸRỌ IRANṢỌ wa ati IRIN-IṢẸ wọn, eyiti o fẹrẹ ba iye owo ti a nta wọn ki ogun Jamani to bẹrẹ nijelo mu.

wọnyi ni diẹ ninu awọn ohun pataki ti o jẹ ki ẸRỌ IRANṢỌ SINGER t'idi awọn ẹrọ iranṣọ miran b'omigbona.

Ikinni.—Ẹwa, itẹju ati idakẹ rọrọ l'ẹnu iṣẹ.

Ikeji.—Irọrun ti o wa lati ri oriṣiriṣi irin iṣẹ rẹ ti o ba bajẹ ra.

Ikẹta.—Ifọwọsọ'ya lati tunṣe nigbakugba lai gba okan gbogbo ẹrọ iranṣọ 'SINGER ibaṣepe a ra lọdọ wa tabi ni Ẹka-ile ọja wa miran.

Wa bere iye owo wọn ni Ile-ọja wa ni Broad Street l'eko nibiti 'Ẹrọ Oyibiri' nl'agogo.

Phone L222, Extensions 2 & 3.
P.O. Box 171.

DADA ADESHIGBIN & SONS,
*Sole Importers Singer Sewing Machines.*

---

## *ILE EGBOGI TITUN.*

Fun irọrun ati anfani gbogbo awọn ti ngbe Olowogbowo, Ita Balogun, Oke-arin Ọfin, Idumata titi lọ de Victoria Road, a ṣi Ṣọbu egbogi titun kan ni Ita Balogun.

*No. 69, Balogun Street,*

Ṣọbu yi jẹ ẹka Ṣọbu nla ti Filipi ni Ajẹlẹ ati Ita Faji—

*Phillips Medicine Store.*

Egbogi ojulowo pọ nibẹ. Ma fi ọpọ silẹ nitosi lọ ra ọwọn ni ọna jijin.

*( Ma ba bọ nihin.)*

Bayi ni a sinku Ajọ yi lọjọ na. Ki Baba le jẹ ki eyiti a o tun da silẹ fi dipo eyi, ninu oṣu *October* ọdunni, le ṣe oju ẹmi olukuluku wa latari anfani.

Ẹgbā Amin kò tó. ! ! !

---

### OLD GRAMMARIAN'S SOCIETY.

*(Literary and Debating Section.)*

A successful debate was held at the Grammar School on Thursday February 22nd. As the Chairman of the Section was one of the speakers, the President of the Society the Rev: E. J. Evans took the chair in his stead. The motion before the House was "That the influence of the Lagos Press is not wholly for good." There was a large attendance of between 70 and 80 including visitors, and the audience included several gentlemen connected with the local Press.

The Proposer was Mr. C. B. Olumuyiwa gave a fluent and earnest speech. He limited the word "Press" to newspapers and called attention to the terms of the motion. The word "Wholly" implied that there was some good in our newspapers. He took the local papers one by one and criticised them impratially through severely.

The "Nigerian Pioneer" was considered by the people as being merely the organ of the Government. A newspaper ought to create public opinion but could the N.P. do this if it is always for the Government and not for the people? The African Messenger, with which the Hon: Opposer was connected (loud laughter) said No. Therefore its influence was not wholly for good. He stated that the Eleko and Franchise difficulties were largely due to newspapers and their Editors.

The "Messenger," also came in for criticism. It had led people one way on the Eleko question and then had turned completely round. Was this good? The Lagos Weekly Record he thought, tried to do good but its language was violent and uncalled for. He then critisised the younger newspapers and spoke very feelingly on the words which were to be found in one of them which were if not indecent, highly undesirable.

The Opposer, Mr. Omololu, then spoke in his usual breezy and witty style. He said he felt like the lawyer who, after listening to a three hours. speech by the opposing consul, got up and said "M lud, I don't think Mr.—has proved his case" and sat down. To which the Judge replied "Niether do I" and gave him the verdict, (laughter). He thought that instead of running down the Press, we ought to congratulate it. The English Press, over 200 years of age was not perfect. Could we expect the Lagos Press to be so? We do not judge a man by his mistakes only. He defended the "Pioneer." The idea of its being controlled by Government was a mistake. It merely sought its information from the Government and used this. He defended the "Messenger." After all a paper must say what it thinks and not to be controlled by popular views. He asserted that on any reasonable view. The influence of the Lagos Press was wholly for good.

A very interesting and spirited discussion then took place. In view of the question at issue, the Chairman threw the discussion open to visitors.

Dr. Savage gave a moving speech. The Press should instruct, enlighten and guide. Was it doing so? There seemed to be a wicked attempt to-day to make people go astray. Editors, to-day were not leaders—they were being pushed from behind. The scurrilous language of some of the papers was prompted solely for the sake of filthy lucre which it brought. He thought it better to have no press than to continue as at present. His speech was loudly applauded.

Mr. Ikoli, then spoke. He said the Press of the whole world was suffering from the domination of the financier. He instanced the Times and other English papers. The Press was not free. The Editor must say what his supporters wanted. A remedy would be the increased support of the Press by the public. At present he considered the influence of the Lagos Press not good.

Mr. Deniga, supported the Opposer. It was natural the Press would make mistakes. He defended the language of the "Eko Akete" and said it was but the reflection of the common language of the people.

Mr. Onajobi and Mr. Olaolan spoke, both supporting the Proposer. The latter stated the even in the last few years, the Press had degenerated, witness the Lagos Weekly Record which used to be a real force for good. One of the younger members then spoke in support of the Opposer—his long words (some of them longer than himself) greatly amused the audience. After the Proposer had replied, the motion was put by the Chairman and carried by a big majority. The debate showed considerable powers of thought and expression among the members and should help to form public opinion as to what should be expected from our Press.

The next debate will be on March 22nd—(the last of the Session) "That this house considers that the Examinations are not a true Test of Education." Proposed by D. A. Onajobi Esq., and Opposer by J. T. N. Cole, Esq., B.L.

---

## Correspondence.

### OLD GRAMMARIAN SOCIETY—SPORT SECTION.

Dear Sir,

At the General Meeting of the above Section held at the Grammar School Hall on Friday 1/12/22 it was decided that each inteding member should pay an Entrance Fee of 2/-6 and secure a Uniform consisting of Jersey and Cap and costing about 8/-.

It was further agreed upon that each member should now pay the sum of 7/-6 viz Entrance Fee 2/-6 and a Deposit of 5/- for the Uniform. As the Uniform will be required to be worn during the Challenge Cup Matches to be played April next, I shall be much obliged if you will kindly send me your Deposit as early as possible.

Yours, Sincerely,
GEO: I. PHILLIPS.
*(Sub-Captain.)*

The Editor "Eko Akete"

---

"EKO AKETE."

A le ri Iwe-Irohin yi ra lọdọ Aṣoju wa.

Ajenifuja Stores, 109 Broad Street, LAGOS.
Ọgbẹni VIDAL R. COLE.

## PRIZE COMPETITION.

SPECIAL PRIZE.—£1 1 0

By The Editor of Eko Akete.

PUZZLE.

When is a D.D. A Man of The World?

CONDITIONS.

1. Competitors must be prepared each to buy half a-dozen copies of Eko Akete issue of the 10th instant in our Office, and distribute same to friends.

2. Entries to be sent in, not later than Wednesday the 14th instant to Ọtunba, c/o The Editor. Result of the Competition will appear in our issue of the 17th instant.

## ESI IDARAYA AWON OMODE.

ẸBUN EKINI.

L. B. Fatoyinbo, 20 Princes Street, 2/-6.
Ayọ Lucas, 6, Kọsọkọ Street, 2/-6.

ẸBUN EKEJI.

H. Olu: Glover Tapa Building Faji Market, 1/-9.
E. F. Ogunmẹfun, 45, Igboṣere Street 1/-9.

ẸBUN ẸKẸTA.

Jacob Adeniyi Orioye, 34, Taiwo Street 1/-6.

Ki awọn Ọmọde ti nwọn jagunmolu yi wa gba Ẹban wọn ni ọjọro *Friday* ọsẹ to mbọ ni agogo mẹrin-abọ ni *Office* wa. [ED—E. A.]


## WANTED.

Young lady required, well educated Speaking fluently Yoruba and English to teach Yoruba about six hours a week to suit pupils convenience. Good pay for right person. Apply at 58, Palm Church Street, not later than the 15th of March, 1923, between the hours of 9 a.m. to 10 a.m. daily.

Lagos, 20th February, 1923.

## ILE OWO-ỌJA RIRANṢẸ TI AWỌN ẸGBẸ OYINBO C. F. HUTHCHINSON NI ILU OYINBO.

Ọgbẹni S. B. VINTURA, Aṣoju awọn Ẹgbẹ Oyinbo yi mura tan lati ranṣẹ awọn Ọja bi *Herbadashery* eyini ni Ṣẹda, Onini, Owu-Ṣẹda alarabara, Ohun-elo awọn Aranṣọ, ati oniruru Ọja bawọnni lati ọdọ awọn Oyinbo rẹ ni Ilu Oyinbo ni owo pọ ọ.

Ọgbẹni na si ni awọn Akẹtẹ *(Felt)* Bata Funfun ati awọn nkan miran daradara pẹlu ni tita ti owo wọn ko ta enia laiya.

Ẹ lọ dan a wo ni Ile-Owo rẹ ni Ita Tinubu, t' o kọjusi Kōtu, l' Eko.


## IGBẸ L' OWO WÀ.

EKURO.

Bi awọn oyinbo ile-ọwọ wọnyi ti gba Ọja (*roduce*) l' ọsẹ yi ni eyi.

Ẹgbẹ Odo-Ọya (Niger Co,)
Jurgens Colonial,
Oyinbo Agbẹra (Lagos Stores)
MacIver, African Products,
Association, John Holt, Miller Bros.
Paterson Zochonis,

£12 15 de £13 fun *ton* kan

EPO.

£21 0 0 ni gbogbo awọn Ẹgbẹ oyinbo ti a darukọ wọnyi gba *ton* kan.

COCOA

Lati £24 de £25 fun *ton* kan bakanna


## The Philharmonic Band.

Awọn oni fere yi nfun pẹtẹ, ilù nwọn si dun bi oyin l' eti.

Owo ti a nfi pe nwọn ko pọ, nwọn ko si kọ lati lọ si ilu ki ilu.

Ẹni ba fẹ nwọn, ko kọ iwe si,

*THE SECRETARY.*
c/o Anfani Motors
The Marina Lagos.

## Mo gbe tana danu Mo gbe miran de.

Ile Egbogi ti a npe ni Iṣẹ Olodumare ti o wa ni ẹgbẹ Iga Oloye Aromirẹ ni Ọbun Eko, kun fun orişirişi awọn Egbogi wọnyi ti o ṣẹṣẹ de :—

Egbogi Kuruna, ati Ọṣẹ rẹ, Egbogi Iṣaka, Jẹdijẹdi, Ela ọmọde, Iba, Ipa ọrẹrẹ ọmọde, Egbogi Ẹda ati Aran Kiniṣa, Egbogi Inu riru iwaṣu, ati fun ọkunrin pẹlu, egbogi ki ara ọkunrin le giri (ko ma ye ẹ) ati orişirişi awọn eyiti a ko le darukọ tan.

Sare lọ sibẹ, ki ọlọra tirẹ, ọpọkuọyọku ni, bi o fẹ lori, oma dọwọ rẹ o,

"Arun ma jogun, ndagba si ẹlẹda rẹ.",

JOSHUA O. ADE: CRAIG,
*Alabojuto.*

## Preachers for To-morrow.

AWỌN ONIWASU ỌLA.

### ROMAN CATHOLIC. (HOLY CROSS)

Masses will be sung by Priests appointed.
Awọn Paddi ti a yan yi o ṣe Isin ni gbogbo akoko wọnyi.

(MORNING)
Masses Isin Aro.
6.30 7.30 8.30 9.30
7.30 8.30 9.30 10.30.

(EVENING.)
Masses (Benediction) Isin Ibukun.
4.45—5.30 6.45—7.30.

St. Michael's (Lafiaji.)
MORNING. 7 a.m.—8 a.m. 8.30 a.m.—9.30 a.m.
EVENNING. 5.45—6.30 p.m.

### ANGLICAN

| Time. | | Preacher. |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Christ Church | The Vicar |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| 9 a.m.— | St. Paul's (Breadfruit) | Ven. Archdeacon. T. A. J. Ogunbiyi |
| 6.30 p.m. | do | Rev. S. J. Gansallo |
| 9 a.m. | St. John's (Aroloya) | Rev. H. V. E. Johnson |
| 6.30 p.m. | do | do |
| 9 a.m. & 4 p.m.- | St. Peter's (Alapako) | Rev. J A Cole |
| 9 a.m. & 6.30 p.m. | Holy Trinity (Ebute Ero.) | |
| 6 a.m.... | St. David's (Jordan) | Rev J A Leigh |

### WESLEYAN

| | | |
|---|---|---|
| 10.30 a.m. | Tinubu | Rev. E. K. Ajai-Ajagbe |
| 7 p.m. | | Rev. D. A. Beckley |
| 10.30 a.m. | Ereko | Rev. S. A. Pears |
| 7 p.m. | | Rev. E. K. Ajai-Ajagbe |
| 10.30 a.m. | Olowogbowo | Rev. E. E. Williams |
| 7 p.m. | | Rev. A. N. Cole |
| 10.30 a.m. | Ọbun Eko | Rev. D. A. Beckley |
| 7 p.m. | | Bro. E. E. Ajọṣẹ |

### AFRICAN (COMMUNION)

| | | |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Jehovah Shalom | Rev. M. B. Newton |
| 7 p.m. | | Bro. I. Martins |
| 9 a.m. | Bethel | Rev. E. A. Akiọla |
| 6.30 p.m. | | Rev. J. W. Bara |
| 10.30 a.m. | African Methodist | Bro. H. A. Williams |
| 4.30 p.m. | | Bro. S. T. Zannu |
| 9 a.m. | Ararọmi (Baptist) | Rev. A. A. Puddicombe |
| 4 p.m. | | do. |

### EBENEZER (BAPTIST).

| | |
|---|---|
| 9 a.m. | Rev. E. C. Alabi |
| 6.30 p.m. | do. |

### BROTHERHOOD

| | | |
|---|---|---|
| 7.30 a.m. | Ilupesi | Bro. Fagbemi Faṣeyi |
| 7 p.m. | | Pastor A. Adedeji Iṣọla |

### St. STEPHEN'S (EPETEDO)

9 a.m. & 4 p.m. Bro. Thomas Akajagbo

### AHMADIA (ISLAM)

6 a.m. Fajir Service Y. P. O. Ṣodẹyinde
5.30 p.m. Open Air Service Imam K. R. Ajọṣẹ (Bamgboṣe Street.)

### COLONIAL CHURCH (ODAN)

8 a.m.—Holy Communion
6.45 p.m.—Evensong and Sermon
Rev. H. A. Lewis


## "VESTA" SEWING MACHINES.

Nos. 3 and 4 Treadle on sale at No. 1[illegible] Odufẹgẹ Street, Ọbadina District Lagos.
At a giving-away price.
A call will convince you.

ALHAJI ỌLỌRUN-NI-MBE.
*General Trader*

## SIMENTI NYAJU !!!

Ọgbẹni Mumuni Ainde ti No. 27, Ita Massey L' Eko ni ojulowo *BIRIKI* fun tita fun ẹnikẹni, owo wọn si rọju.

Ẹnikẹni to ba nfẹ ba Ọgbẹni na ra awọn *BIRIKI* yi le lọ ke si i ni adugbo rẹ.

Ki a ri nyin o, Ẹnikeji, Ijafara lewu.

## W' O BI, ẸNIKEJI, OJU L' ỌRỌ WÀ!!

Maṣini Aranṣọ ti a npe ni "MUNDLOS" wa fun tita niti Ọgbẹni J. S. JOHNSON ti 16, Ita ọja Ajaṣẹ, ni owo ọpọku-ọyọku.

Ni Ile-iwo oriṣiriṣi ọja ti
Ọgbẹni ARNOLD SCHLESINGER,
Oniṣowo ara Jamani ni
Ita 7, Labinjọ, leti Ita William
lẹ gbe le ri awọn ẹrọ RECORDS ohun orin ijọ to ṣẹṣẹ de ra ati awọn Ẹrọ wọnyi.

Ẹrọ ohun-orin GRAMOPHONE
Kẹkẹ-olo-gere BICYCLE
Awo Abọmafa ENAMELWARES
Waji BLUE ati ogunlọgọ ọja miran.
Ẹ sure tete lọ ra ti nyin nibẹ.

## SOMETHING TO YOUR TASTE.

Mr. J. D. Olayaha, Painting Contractor and General Decorator is prepared to undertaken all aint-works of every description to the entire atisfaction of Clients.

He is also an expert in sign-board work; has orked for many important European Firms in own notably, the Firm of P. Z. and also the local P. W. D.

Terms reasonable.

For particulars,

Apply at 16, Mogaji Lane, Ẹpẹtẹdo.

A trial will convince you.

---

## ỌMỌ NI YIO ṢẸHIN DE Ẹ.

"Ẹwa wo" "POSI Alarabara"

Ile Igbẹhin lọdọ J. T. Cole,

Gbẹna-gbẹna ni ita 40, Ofin Canal,

Ihin ko to afẹjuba

A le gbani ni awin ti a ba san idaji owo.

---

Are you suffering from impotent sexual & nervous prostration and impaired vitality. Use Muicacithin pills and get instant relief. It makes a man a man. In short it will rejuvenate you, also unsurpassed remedy for female Neurasthenia. Disturbed menstruation, sterlity, etc., etc. Its effect is sure and permanent, in bottle of 50 pills 5/- in bottle of 100 pills 7/- are you a sufferer of that troublesome Asthma? Why dont you use Asthamacid and get rid of it at once, in bottle 5/6. These medicines are German preparations and always give satisfactory results.

"Ajenifuja" Store Vidal R. Cole

P. O. Box 201; 109 Broad Street Lagos

---

## Ọgbẹni H. CAMPOS,

Oniṣowo ni 7, Campbell, Street L'Eko.

u wa! iwọsi oniruru onjẹ-panu (*Provisions*) ni tita: Ṣẹrẹkẹ ṣin ni awọn Itan-Ẹlẹdẹ (*Hams*) ti o ni: Ọti *Wine* ati awọn Ọti miran to ni nda ni l' ọrun:

Ẹ tete lọra ti nyin nibẹ; awọn Ile-ọja rẹ miran tun mbẹ ni 63, Ọdunlami Street ati 2, Onikẹpọ Street Ita Faji l'Eko

Ohun a jẹ lo mba ni lọ.

## NOTICE.

When replying advertisers, please mention "Eko Akete"

---

## AKIYESI.

Ti ẹ ba fẹ lọ si ọdọ awọn ti o polowo ọja sinu Iwe-irohin yi, ẹ jare ẹ sọ pe ninu iwe-irohin Eko Akete ni ẹ ti ri ipolowọ ọja na ka.

---

## First Class Dressmaking!!!

Mrs. Said Fattal, trained in Paris, begs to offer her professional services to the public.

Latest modes at moderate charges satisfaction gauranteed. Call at once at

117, Victoria Road,

Lagos, Nigeria.

---

## PAGIDARI!

*Olokiki* S. FRANCIS LAWANI *Saka-jojo.*

Onişowo ni Victoria Road ni wabi-wọsi ohun elo, fun Ọmọge ati Ọmọdẹ-m'ẹṣọ ti o si nta ni ita oloko o-gbowo.

O si tun ni aye pataki kan ninu ile oja na, ti a nṣe Gbajamọ fun ni, ni owo-ti-kotanı-lara, bi ṣile kan, sisi, tabi tọrọ.

Egbogi orişi-rişi iwosan onirunru aisan, Ipara olo-orun, ati agbọrun Jigin oju, ati nkan mere-mere pọ to wọbu nibẹ.

Ikan-o-jọkan irin iṣẹ ati Egbogi ti a fi nya *Photo* aworan wa nibẹ ni ọpọku yọku.

Oniru-nru wosiwosi ti a ko le ka tan pọ nibẹ bere ohun-ko-hun ti o ba nfẹ yio pese rẹ fun ọ.

O ngbero laipẹ, lati şi ile Erọ Idan Awoşeju ti a npe ni *(Cinema)* ni Great Bridge Street, Idumagbo.

Şoroko a gbe şeranwo ni igbati o ba şi ibẹ.

Irohin ko to afojuba.

*P.O.Box 159* *Phone 214*

## ALASE LEATHER FACTORY.

"ILE ALAWỌ."

Sole-Leather tanned in a most modern style and Upper-Leather prepared in all colours, namely:—Black, White, Red, Yellow and Green, are obtainable at very cheap prices.




Awọ Bata ni ọpọku ọyọku. Kọwe ṣọwọ yala ni ede Yoruba tabi ti Gẹsi pẹlu owo si:—

E. B. BEYIOKU-ALASẸ
108, Moloney Bridge St.
P. O. Box 368, Lagos, Nigeria.
*Telegrams:*—Alawọbata, Eko.

29. Oripasan Lane,
King's Quarter, Isale Eko,
Lagos, Nigeria.

THIS IS TO CERTIFY THAT I have many years' experience in Dirty Window Cleaning, Changing of Plan Window to any colour or kind of Pattern in Flowers cleaning or white washing of wall to any kind as Distemper colors etc., Cleaning and Washing of a Dirty House to new, by Vanish and assorted kinds and Pattern of Colour to Paint House and putty and painting of Corrugated roof to red.

For Terms, etc, apply to the above address.

**Lawani T. Mogall,**
*General Manager.*

Ọgbẹni ERIC: JOS: W. LEWIS.

Jẹ eniti o gba iwe-aṣẹ Ogun pipo, o si "Ṣọ Egbogi Oyinbo si 14, Ita Tinubu nile ọgb J. L. Williams Ologbe, ati si 34, Ita Ọbadina Ya Ọgbẹni na ṣetan lati da enia lohun lọna iṣẹ r

Lati *Monday* de *Saturday*.

7.30 a.m de 12.30 p.m    2 p.m de 8 p.m
Ni ọjọ ọsẹ lati 6.30 a.m de 8 30 a.m
Owo to ngba ko ta enia lara, ẹ lọ bẹwo,
Ogun rẹ jire.

GIDIGBO! GIDIGBO!! HEYA!!!



Awọn RECORDS to nkọrin lede YORUBA pọ to wọbu ni ile owo.

MANN POOLE & COMPANY LTD.
8, TINUBU SQUARE, LAGOS.

Ki la ti nṣ' oku l' ọrun?
Ki la ti nṣ' ori nile Iku?
Tutu tabi Gbigbẹ?

Ọpọkuyọku si ni, wa ṣa eyi to wu ọ ni:—
8, TINUBU SQUARE, LAGOS.


PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING WORKS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.